OJO ADISA NAP PAIR (1&54)
Mo ki eyinti e ra 48xx ni wk 30 ku orire 4 Naps ns tun mbo ni wk33 fi N6 ranse fun tirę Banka meta wa walosase N5 ni tete kowe fi owo ranse si-:
OJO ADISA,
N4/273 Ade Ọyọ
Ibadan

Imọlẹ Owurọ

Esin oro wa "IMOLE DE OKUNKUN PARADA"

UNITY NAPS
For 3 sure draws in Wk 31 try to see The Manager Unity Pools House E4/226, Gbelekale Ibadan
See him with N5 before 2 p. m. on Saturday
3 20 32

Independent Paper VOL. XIII No 629 SATURDAY MARCH 2 — FRIDAY MARCH 8, 1974 4K. (KOBỌ MERIN)

# IYAWO ṢOJA GBE MAJELE JẸ, ALE M'ORILEGBO

IROHIN lati ilu Ibinni fi ye wa pe iṣẹlẹ buburu kan ṣẹlẹ ni ipari ọsẹ ti o kọja ni Bareke Ṣọja ti nwọn npe ni Ekenwan Barracks, nipa pe iyawo Ṣọja kan ti ọkọ rẹ ko si nile gbe majele jẹ, o si pa araa rẹ nitoripe nwọn ka ọkunrin Ṣọja miran mọ ọn l'ori mbiti o ti mba a lopọ lori akete ọkọ rẹ.

A gbọ pe ọko obinrin na ti o jẹ Ṣajẹnti ninu iṣẹ Ologun wa ni ilu Eko nibiti o ti nkẹkọ nipa iṣẹ rẹ lọwọ ni akoko ti iṣẹle na ṣẹlẹ ni Bareke wọn nilu Ibinni.

Irohin sọ pe, bi ọrọ na ṣe jẹ ni pe, ni ọganjọ oru ti gbogbo aladugbo ti sun tan, ni onile keji ti o mu ojule ti iyawo Ṣọja na bere si gbọ ohun enia meji ti nwọn ko sọrọ soke lati inu iyara iyawo Ṣọja na.

Irohin fi kun un pe, nitori ọran yi ni onile keji na fi jade wa si ojule iyawo Ṣọja na ti o si ṣilẹkun mọ ọn l'ori.

Siwaju si i, Irohin sọ pe nṣe ni o bi ọkunrin kan ti o fi ọkan ninu aṣọ iyawo Ṣọja na ṣe ẹlẹdi pẹlu ami ti o jọ bi ẹni pe awọn mejeeji ṣẹṣẹ ba araa wọn lopọ tan ni. Irohin na ṣo pe nṣe ni ọkan ọkunrin na balẹ bi ẹni

(Woju ewe kẹjọ)



ỌMỌ ỌBA R. S. ADEMILUYI
"Ẹdugbe Eto"



Aworan oke yi nṣe afihan omuwẹ olokiki ọmọ ilẹ Gẹẹsi kan Pat Beavan lati ilu Wales, ẹniti o gba ami goolu—ipo kini ni ibi are idaraya ti ilẹ ti mba Gẹẹsi ṣepọ ni ilu Christchurch ni ilẹ New Zealand ni aipẹ yi

## Ademiluyi bo ninu ejo

ILE ẹjọ giga kan ni Ibadan ti o nṣẹjọ ẹsun idimọlu, ati jijale owo ti o le ni ẹẹdẹgbẹta Naira (N5,000) ti a fi kan awọn enia mẹfa kan ti ngbe ni Ibadan, ti da gbajumọ oludasilẹ ile ẹkọ giga kan ni Ibadan Ọmọ-Ọba Robert Ṣiyanbọla Ademiluyi ti adape rẹ njẹ "ẸDUGBẸ ETO" silẹ pe ki o maa lọ sile rẹ ni alaafia nitoripe ẹsun na ko gbun un lọwọ tabi gbun un l'ẹsẹ.

Ṣaaju, awọn afẹsunkanni ni o fi ẹsun kan pe Ọmọ Ọba na ti o ngbe ni N4/96 Yemẹtu Alaadọrin Ibadan. Lasunkanmi Akande ti ngbo ile Afunlehin Isale Alufaa Ibadan, Layiwọla Adegun ati Kameru Iṣọla ti abule Alabuke ati Salami Ọmọteṣọ ti o ngbe ni N5/293B Gbenla Ibadan ati Raufu Akanni ni nwọn dimọpọ fi ayuuyuu gba owo ilẹ Aṣejirẹ ti awọn olomi lo bi ẹni pe awọn ni o ni ilẹ na.

Ni akoko ẹjọ na, awọn enia kan ti o sọ pe awọn ni awon ni ilẹ na jẹri gbe Ijọba pe awọn ko ran ẹnikẹni lati ba awon gba owo na, bẹẹni awọn ko si mọ won pẹlu.

Ninu idajọ re Adajọ ile ẹjọ na Ọlọla Olu Ayọọla sọ pe ẹri ti o wa niwaju ile ẹjọ fi idi ẹsun na mulẹ pe awọn merin ninu awọn ọdaran na jebi ẹsun na. Awon

(Woju ewe kẹjọ)

# ATIORO OMO ATIALA

## EWE IWOYI (1)

Bi a ba nwi
A dabi owe
B'aa si wi
A dabi ija
Ki l'a o ti şe wç
T'a o fi k'ole aiye ja!
Bi a ri t'a awi
OGUN!
Bi a ri t'a o wi
OTE!
Ki l'o kuku dun bi
K'a ri, k'a wi?
Bi a ba wi tan
K'aiye o tata sọ
Ohun gbogbo
T'o ba fee sọ si ni.
Nje gbogbo enia pata
Ti ngbọ nasia yi,
Nasia pataki
L'o delç yi
Fun gbogbo janmna
Nitori ohun a fee wi
Gbogbo wa l'o mba wi
At'akọ, at'abo
E je ki kaluku fiyesile
Şe ọrọ na kii sajeji
Fun enikọọkan wa.
A ti sọ ọ ri,
A ti wi i nigbakan




Fun gbogbo wa;
A ti soro yi ri
Nipa iwa eşubeleke
T'ewe iwoyi nhu,
A si ti kesi
Gbogbo bimọbim
Pe, ki nwọn gbiyanju
Lati t'oran omo won şe
Nitori iwa eşubeleke
Ti gbogbo ewe nhu:
Şugbọn aanu şe wa
Pe, bi a ti nwi to
Awon ewe ko gbo;
O dun wa l'aduniu
Pe, bi a ti kilo to
Gbogbo wọn ko kuku
gba;
Kaka ki nwọn gba ilọ;
Kaka ki nwọn dękun
Iwa alagidi;
Kaka ki nwọn ronu
Ki nwọn tun'wa won şe,
Nşe ni nwọn nwaiyami
Niau a nhuwakiwa.

Tabi, emi l'e pe k'a wi?
Emi l'ę pe ka sọ?
Eao lę o mo
Ninu iwa eşubeleke
T'ọmọ iwoyi nhu?
Tabi taani
Ko wo enu ilę
Ti ko wo ęnu ękọ?
Taani ko nri
Iwa esubeleke
Ti ngbile laarin wọn
B'o se 'de 'bigbogbo?
Omọ ko bọwọ f'obi mọ,
Ọmọ işe nko asę ogo,
Omo keke'e nsọrọ
O l'ęnu agba orun?
Omo kekere mbinu aitọ
O npe ęgbę baba rę
Ni digbolugi?
Nwọn ni
Omode l'o gbon
Agba ko l'ogbon ninu
Nwon ni
B'omi gbigbona
Ba dapọ mọ tutu
Ọmode le yanju 'ę?
Nwọn ni oke gegara
Ti agbalagba ba gun ti
Kiakia l'ọmọde ode oni
Yio gun un d'ori!
Nwọn ni
Ọgbọn atijọ l'agba gbọn
Nwọn ko lagbara eto
Bi ewe;
Nwọn ni nitori
Agba l'o l'ana
Ọmọde ni yio ni to—
morrow!
E roju aiye
Tabęę ri i?
E r'ironu ęda
Tabęę r'ironu ęda!

Enia t'o fęę gori itę
T'o ni t'agba ko too
pọnle!
Eni t'o fęę d'aşaaju
T'o ni t'agba bawo!
Enia t'o fęę joga
Ti mba dukia jẹ!
Eni ti yio jọba
T'o nrun ogun
Ti nwọn fi i ş'ola Ọba!
Enia t'o fęe d'ijoye
T'o npe gbogbo ilu
l'omuge!
T'o ni t'ogbọn l'an'o si
T'o nu oun nikan lọ!
Eni t'o fęę ş'aşaaju
Ti ko pa ofin mọ!
Enia t'o pe 'raa rę
l'olaju
T'o ntapa s'ofin!
Nję b'iru awọn wọnyi
Ba d'ọga tan
Nwọn ko rai balujẹ!
Nję bi nwọn jọba tan
Nwọn ko nii yaso!
Bi nwọn d'ijoye tan
Nwọn ko nii ya'bọn!
Nje bi nwọn ba
Gori oke tente
Nwọn ko ni d'ęran
Si gbogbo ilu l'ęrun!
Nję gbogbo agba
T'o ba wa laiye
Ko nii r'orun apapa—
ndodo
Gegẹ bi itan awọn
Ọdọmọde ilu
Ti nwọn gbimọpọ
Lati pa gbogbo agba ilu
Nitori nwọn sọ pe
Agba ko jẹ ki
Awọn r'aye paşe!
E maa ronu l'ori eyi
K'o fi d'ęsę t'o mbọ.

ỌLỌLA ATIORO

# Egunlola gba ife eye

Ni ogunjọ oşu keji ọdun yi ni awọn ọmọ ile-iwe Paku—Awaye Baptist United fi ere ọlọdọdọọdun da awọn enia laraya lori papa işere wọn ni Awaye leti Egbęda ni agbegbe Ibadan.

Ọgbęni E.O. Fawumi ti işe ọga ile iwe na ati Ọgbęni Lanrewaju Oni, ti apele re nje 'AKIRA BABA O' ti işe oga alamojuto ere na gbogbo agbara wọn ti o si mu ki ere na larinrin pupọ.

Awọn ile ti o fi aga gbaga na ni ile Akindeji, ile Akintola, ile Egunlọla ati ile Ojo, sugbọn ile ti o gba ife eye na ni ile Egunlọla ti Ọgbęni Banji Ọpa—kunle ati Iyafin Ade—goke işe ọga wọn.

Awọn alejo pataki—pataki ti o wa nibę ko niye; ninu won ni alaga ere na Ọgbęni S. O. Akintọla lati Ibadan, Ọgbęni Lekan Ọlapọju, Iyafin C. O Şiyanbọla, Oloye Akindeji; Ọgbęni Egunlola, Ọgbęni Ojo ati Ọgbęni S. O Abiola,

Apapọ ero ti o wa wo ere na to ọọdunrun,

## IKILỌ

EYI ni lati şe ikilọ fun gbogbo enia ti o ba fę tabi ti o ti şe ohunkohun l'ori ilę FEDỌ-GBO, AIPO ati ỌBAMOWO ti nwọn ję enia Ogbomọşọ pe ki iru awọn enia bęę l'ori ilę awọn ębi ti a darukọ şoke yi nitoripe a gbọ pe ęnikan ti wọ ori ilę na o si ti ba awọn nkan ọgbin ọrọ aje olowo iyebiye ję nibę.

Nitorina a fę ki iru ęni bęę şiwọ lati tun şe ohunkohun l'ori ilę na ki o si san ęgbarun Naira (N10,.000) fun ębi kọọkan fun wiwọ ti o wọ ile wọn lai tọ bibęękọ, a o şe ętọ fun un l'oruko awọn ębi na gegębi ofin ti wi.

YINKA AYỌ—
ỌLA&Co
(SOLICITORS)
15/2/74



Aworan oke yi nşe afihan ara awọn ohun işire nigba odun Keresi ti awọn ile ise sese gbejade nigbakan bi nwọn ti nfi han awọn oniwerohin. Ọpọ ninu nkan wonyi ję ohun isire ọmọde. Iru nkan wọnyi kanna ni o wa ninu aworan ti isalę



AKEDE ONA IYE

# Lo Igbagbo Re Fun Atunse

LATI OWO WOLI S I OWOEYE



WOLI S I OWOEYE

"ARA, bi a tile mu enia ninu işubu kan, ki ęnyin ti işe ti ęmi ki o mu iru ęni bęę bo sipo ni ęmi iwa tutu: Ki iwo tikararę maa kiyesara ki a ma baa dan iwo na wo pęlu" Galatia 6, 1.

Melo ni a o ka ninu Onigbagbo ode oni ti nwon gba ęsin ni gbi—gbona rabęę ti alaye ęnikęni kii jo won l'oju bikoşe lati maa fi awon enia ti o ku dię ki a to fun şe yęyę?

Nipa eyi, iru awon enia bee a maa ję alatako Jesu Kristi nitori-pe bi eni ti nwon ko ba ni ife si ba nso ore, Olorun nipasę Jesu Kristi, idi ni won yio tumo re si ki oro eru Iru enia ti nsoro Jesu na ma baa şe fi idi mule laarin enia ninu aiye:

Şugbon iru awon enia bee kii ranti pe, ninu işubu ni aiye ti wa lati odo Adamu ati Efa wa; bee ni o si ye ki awon paapaa ranti işubu ti awon alara ki nwon too gba esin Igbagbo, ki nwon si mo pe kaka ti awon iba fi maa fi enia ti o ba fee şubu şe yeye, nşe l'o ye ki nwon mua gbiyanju lati mu ese won duro:

Tabi kini a ri l'oni? Opę ko ha nwo iru awon enia kan ti nşubu nipa ti ara, ti nwon si nda yeye won sile lehin isin tabi ni ile won ? Iru awon wonyi ni oro Olorun tun atenumo, ti o si nran iwo paapaa leti l'oni lati maşe rope eniti o şubu ko le dide mo

Nitorina, iwo ti o mo pe enikan şubu nse ni ki o fi ona ti yio gba dide han an ki iwo paapaa ma baa di eru ese ti kii şe t'ire ra. Fi itan kekere yi se iwa hu :

ITAN

NI akoko kan, ore meta kan wa ti nwon je onişowo; nwon si ti pinnu lati ji lo si irinajo ni ojo keji gegebi işe won. Oruko ekini nje Ife, ekeji nje Suuru eketa si nje Kokanmi

Ninu ile kanna ni Suuru ati Kokanmi ngbe, oto si ni ile ti Ife: Şugbon gegebi adehun, Ife tete ji lọọ ba won nile.

Nwon ko tii ji nigbati Ife de ile won. Nigbati

Nibiti Ifę ti nlo, Okun ina monamona ti o jalulę gbe e şubu ko si le dide. Nibiti o ti nyilę ni Kokanmi ati Suuru ba a. Suuru kigbe: o ni oun yio pada sile lo ipe awon enia,

Şugbon Kokanmi gbe apo tire, o nlo, o ni iya ti o ye ki o je Ifę na l'o nję ę lo nni teripe ko duro de oun. Şugbon Suuru sare pada sile lati pe awon oşişę ile işę monamona,

Gegebi a ti ko so o duro die ti nwon ko tete jade, o ro ni okan re pe, asiko ni işe, ki awon rete de ibiti awon yio si tete ri oja ra ni o dara.

Ni aifa oro gun lo titi, Ifę kuku ko apo awon meteeta pe oun yio maa lo niwaju si odo awon onibara won ki oun si maa ra oja sile de won.

Kokanmi jowo eruko re nigbati o ba Ifę ninu ijamba yi, nşe ni o koja lo ni egbe re. Şugbon bi Kokanmi ti rin die ni oun paapaa kolu iru okun ina yi kanna ti o lagbara ju iru eyiti Ife kolu lo, Kokanmi si gba ibe ku bamubamu,

Şugbon atunşe wa fun Ife nitori ina gbe e ju sapakan lasan ni, Suuru ti o loo sare pe awon onişe monamona wa ko si ni ifarapa kankan.

Nje, eko wo ni iwo omo enia ko nibi oro awon meteeta wonyi ? Ara eko ti itan yi nko wa ni lati je ki emi iran enikeji lowo gbile ninu wa, nitoripe bi o ba so pe işubu enikeji re ko kan o, boya iru iwa ti o hu si na ni yio fa işubu tire na pelu,

Nitorina ni ese keji ninu iwe Galatia fi nso pe, "E maa ru eru omonikeji nyin ki e si fi bee mu ofin Kristi şe"

Iwo omo enia, ti Oluwa fun o ni ogbon ati oye, ma şe lo o fun işubu ati ibaje enia, kaka bęę, e maa fi iwa tutu ati suuru mu awon ti nwon şina bo s'ipo, niwon igbati aşişe iru enia bęę ti iwo mo koi ti i la ti iku lo nitoripe ayipada le ba ipo ęnikęni niwon igbati a si wa l'aiye ęşę yi, yala şi rere tabi si bub ru:

ADURA

Oluwa, jowo fun mi ni emi suuru ati iwa pęlę lati le mu ona mi mo taara niwaju re. Oluwa mu awon ti o şubu duro ki nwon le yipada kuro ninu aşişe won, Amin.

## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10'562 Joseph Akinnagbe, Okitipupa
10,563 Mufutau Atanda, Ikeja
10,564 Mathew Gbenjo, Ilero
10;565 Joshua Abodunrin, Şomolu
10,566 Samson Ogunşina, Ibadan
10,567 Solomon Ikuforiji, Ilesa
10,568 Emmanuel Olaopa, Ibadan
10,569 Taiwo Oladeji Ibadan
10,570 Raimi Owolabi, Eko
10 571 Aderinola Okunola, Okuku
10,572 Elkanah Akinloye Yaba
10,573 Sule Raifu, Ikeja
10,574 C. Adeşola Sodipo Ileşa
10,575 Waidi Abidogun, Ogbomoşo
10,576 Disu Akanji Ilorin
10.577 Olakunle Bogunjoko, Eko
10.578 L.A. Akano, Ibadan
10,579 John Dare, Eko

FUN IGBEGA EDE ATI AŞA YORUBA
DI
**Omo Egbe Imole Owuro**
(Iwe idi omo Ęgbe)

Oruko re: ______

Adirẹsi re: ______

Omo ilu ti o je: ______

Jawe yi ki o si poosu re si
DOKUN AJADI
(Akowe Ęgbe)
P. M. B. 5230, Ibadan



Aworan oke yi nse afihan awon akanse meji kan Buchanan (lapa osi) pelu Ismeel Laguna ni akoko ija won kan.

# AGEKURU ITAN ILU Ogbomoso

## (32)



OBA LAYODE KEJI
Ṣ;hun Ijẹta ni Ogbomọṣọ

### IKOYI

Biotilẹjẹpe ara Ikoyi ko wa si Ogbomọṣọ nigbati Ikoyi tu ṣugbọn sibẹ o yẹ ki a sọ diẹ ninu itan Ikoyi, nitori nigbati a npe Olugbọn, ati Arẹsa, Onikoyi ni a npe ṣe ẹkẹta wọn ni Ẹku—Osi.

Bi itan Ikoyi ti lọ niyi: A gbọ pe nigbati ilẹ Yoruba bajẹ ti Tapa le Alaafin Onigbogi lọ si ilẹ Ibariba, lati ilẹ Ibariba de Ṣaki, lati Ṣaki de Igboho, ati lati Igboho pada si Ọyọ nipa Ọba Mọrọ.

Ko pe ti Ọba Mọrọ pada de Ọyọ Ile ni awọn Ẹku—Osi lọ ki Alaafin ku ewu abọ. Itan sọ pe ni akoko na ni Ọba Mọrọ pa Elenre Ọba Igbọn. A ko mọ ẹṣẹ ti o da ti a fi pa a. Lẹhin eyi ni awọn Ẹku—Osi wipe awọn ko sin Alaafin mọ. Gbogbo ọna ti awọn Ẹku—Osi ti ngba lọ si Ọyọ di Igbẹ, tobẹ ti enia ko le mọ oju ọna mọ. Ni akoko yi ni ẹnikan ti a npe ni Jẹgbẹ ọmọ Alaafin dẹgbẹ lo si ẹgbe Ikoyi.

Ni akoko naa ni aluba (Ayọkẹlẹ) (Infu-lonza) kan de si Ẹku-Osi, awọn enia wa ro pe nitori isin Alaafin ti awọn kọ silẹ ni ayọkẹlẹ yi fi de. Nitorinaa nwọn pe ara wọn jọ nwọn si kọri si ọna Ọyọ. Nigbati nwọn de earin kan, nwọn ko mọ ọna mọ.

Nitiu nwọn nṣe rannu-rannu kiri ni nwọn ba Jẹgbẹ ni ibi ileba re, nwọn si beere ọna Ọyọ lọwọ re, o si wipe ki nwọn fun oun ni nkan ki oun too fi ọna han wọn, nwọn si da nkan jọ fun un bi owo, aṣọ, ilẹkẹ, ade ati bẹẹbẹẹ lọ: o gbe gba gbogbo re o si fi ọna han wọn de ẹnu odi Ọyọ.

Nigbati o de ẹnu odi, o mu ki nwọn duro ni ẹhin odi, o si kọri si ọdọ Ọba lati sọ ohun ti o ri fun un. Nigbati o sọ gbogbo nkan yi fun Ọba tan, Ọba si wipe, ohun ti o ba ri ki o maa mu u, laimọ pe nkan pataki ni o ri.

Ṣugbọn ohun ti o mu

LATI ỌWỌ OLOYE S. O. BADA

ki Ọba wi bẹẹ nipe. Jẹgbẹ ti ri idanwo nipa pe bi o ba pa erin ti o lọ si ile pe oun pa erin, ti gbogbo ilu wa lati ṣa eran, ki nwọn to de ibẹ, erin a si ti dide a si lọ.

Nitorinaa ni oba fi wipe ki o maa fi ọwọ mu un. Ni ikẹhin ni oba wipe ki o lọ ko awọn enia na wa; o ko wọn wa, Ọba si wipe, "Nibo ni o ti ko eyi?" Lati igbanaa ni a ti npe ilu ti o tẹ ni Ikoyi, oun naa ni a si npe ni Onikoyi (Ẹniko-yi) titi di oni

Olubẹsin Oẹugbera ni oruko rẹ ṣugbọn oriki ni Jẹgbẹ je itumọ oriki naa ni Jẹgbẹ bi eniti ara rọ. Nitori nigba-gbogbo ni Olubẹsin maa nmọ loto bi olowo. Nitorinaa ni awọn enia fi fi oriki naa fun un

Lẹhin ti ALAAFIN ri ohun ti Jẹgbẹ ti se o wi fun un pe lati oni lọ iwọ ni yio maa se Aṣaaju awọn Ẹku-Osi wa si Ọyọ nigbakungba ti nwọn ba ni lati wa si Ọyọ fun ọdun asingba tabi ohunkohun ati pe iwọ ni yio maa ṣe Aṣaaju Ẹku—Osi nibi ogun ti oun ba si fun Ẹku-Osi. Ati pe ade ti o gba lọwọ awọn ọba ti o fi ọna han, oun yọọda ode na

fun un ki o maa de e Lati igbanaa ni Onikoyi ti nde ade titi di oni yi

Eto olori ogun Ẹku-Osi naa si wa nibẹ titi di igbati Ọba Ajagbo fi di oye Aare—Ona-Kakanfo silẹ ni ogun odun 1600, ni ọdun ti a tẹ ilu Ogbomọṣọ.



ỌBA OYEWUMI
Ṣẹhun Ogbomọṣọ Lati ọdun 1916


## IWE OLOYE BADA

Bi ẹnikẹni ba ra iwe itan Ṣaki to mẹwa dipo Naira marun, yio san Naira mẹrin abọ Ẹni ba ra iwe Igba Ewe Jesu mọwa yio san Naira meji, ati kọbọ mẹdogun.

IGBE AIYE ỌMỌ ENI SORO -Ẹyọkan jẹ 12k, ẹyọ mẹwa je Naira kan. Iwe na kọ ni bi a ṣe le pari ẹkọ, bi a ṣe le ṣe iṣẹ. ki a ni aya, ki a ni ọmọ, ki a kọ ọmọ ni iwe ati bẹẹbẹẹ lọ lai yọ silẹ rara.

ETO KANSULU ATI ETO ẸGBẸ—O kọ ni bi a ṣe nṣe Kansulu ati ẹgbẹ: Ka iwe na Iwọ yio ri i pe bẹẹ ni o ri, 18k ni ẹyọkan. N1.40 ni ẹyọ mẹwa.

Mo fẹ ki awọn onibara mi maa kọ orukọ ati adress wọn yanju nitori awọn meji kan ti ranṣẹ iwe ni ọdọ mi ti mo si fi iwe ranṣẹ si, Sugbọn ti nwọn tun da iwe pada si mi ni Dr. Rev, W A Aleesan Alias Oyemẹkun 24 Ereko Street, Lagos ati David Ọlaṣẹhinde 50, Docemo Street, Lagos ki nwọn kọ addres wọn yanju, ki nwọn si fi owo iposu, ti yio to gbe e ti ise 32k fun register ranṣẹ

Maa fi owo iwe yowu ti o fẹ ṣowọ si
S O Bada,
P O. Box 26
Ṣaki


# 20 32 35

# Oga Ọlopa jare ẹsun dide aja mu onitakisin

ILE ẹjọ giga kan ni Ibadan labẹ aga Ọlọla Olu Ayọola ti tu ẹjọ ẹsun "O dẹ aja rẹ mu mi" ti ọkunrin awakọ takisi kan fi kan Oga Ọlọpa kan ka.

Ọkunrin awakọ na Ọgbẹni A. Salami ti o ngbe ni adugbo Ekotẹdo nilu Ibadan ni o pe Oga Ọlọpa kan D. S. P. A. Fafowora l'ẹjọ pe o paṣẹ pe ki aja rẹ bu oun jẹ, nipa eyiti o fi ẹsun kan pe ibujẹ aja Ọlọpa na fi sọ oun di lai lee ṣe baba ọmọ mọ, o si nrọ ile ẹjọ lati gba ẹgbẹarun Naira owo itanran fun oun lọwọ Oga Ọlọpa na

Ninu ẹjọ ti o pe na, Ọgbẹni Salami fi ẹsun kan pe ni ọjọ kọkanla oṣu keje ọdun 1972 ni iṣẹlẹ na ṣẹlẹ ni adugbo Bodija nigbati oun nlọ bẹ ẹ pe ki o fun ni iwe ẹnna ọkọ oun ti o sọ pe Oga Ọlọpa na ṣi l'ara ọkọ oun ni ẹjọ na.

Ọgbẹni Salami sọ pe ni akoko ebẹ na ni Oga Ọlọpa na paṣẹ fun aja rẹ pe ki o mu oun, ti oun si fi di akura.

Ṣugbọn Oga Ọlọpa na sọ fun ile ẹjọ pe oun kọ ni oun ni aja ti o bu awakọ na jẹ.

Ninu idajọ rẹ ti o

(Woju ewe kefa)



# Ile Igbebi ni Ijabe

Awọn Ẹgbẹ Musulumi ti iha Ila-Oorun Ariwa Ọṣun ti ko irinwo Naira ( N400 ) jọ fun kikọ ile igbẹbi kan si ilu Ijabẹ ni agbegbe Odo Ọtin.

Laipẹ yi ni awọn ri owo na kojọ ninu ipade kan ti Ẹgbẹ na ṣe labẹ Alaga Alhaji O. M. Adewoyin ti o jẹ igbakeji Baba ẹgbẹ na.

Onijabẹ ti Ijabẹ Ọba Sunmọru Oyewale yin awọn enia na fun iwa ifọwọsowọpọ wọn nipa eyiti ilu Ijabẹ yio fi ni iru nkan anfani bẹẹ,

Ọba na ṣipaya pe awọn ara ilu oun ti ko owo ti o le ni ẹgba arin Naira (N8,000) jọ fun kikọ Gbọngan kan si ilu ijabẹ, ati pe enikọọkan t'o ba to iwe ori igba ti gba lati da Naira m runmarun ki ero na le tete jọ.

IWE IGBAELODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agua 10k
2 Kurani esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (10k)
4. Zabura ati itumọ (35k)
5. Zabura Yoruba (30k)
6. Iwe Aiye Akamara (40k)
Iwe owe enia ṣoro 40k
7. Adedẹwẹ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1. 50)
10 Kekere(30k)
11 Iwe oogun iwosan (N1. 5) Kekere (35k)
12 Itan Anabi ati Yisa (55k)
13 English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) R[illegible]NṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a, Odoye Ibadan.

(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi Iṣin St Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin



KERE O! KERE O!!

*Bi o ba je onisowo ti o nfe ki oja re maa ta; ti o si nfe ki oja re gbajumo kari aiye gegebi iwe irohin IMỌLE OWURO ti gbajumo; darapo pelu awon enia atata ti o npolowo oja won sinu Imole Owuro.*

*Fun alaye ekunrere nipa bi o se nilati se e ati iye ti o nilati san; wa sile ise wa tabi ki o kowe si:*

**Advertisement Manager**
**(Imole Owuro)**
**N4/496B Yemetu Aladorin**
**P. M. B. 5230**
**badan.**

# Awon roworowo Na Olopa Ni inakuna



IROHIN lati ilu Aba ni ipinlẹ Aarigungun Ila-Oorun fi ye wa pe agbaaragba ija kan ṣẹlẹ laarin awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ ati awọn rọworowo ni ọja Eke—oha ni ilu na na nipa eyiti Ọga awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ na fi di ero ile iwosan ilu Aba bayi nibiti o ti ngba itọju.

Ni ipari ọsẹ ti o kọja ni iṣẹlẹ na ṣẹlẹ ni ilu Aba. Nwọn ni lẹhin ti owo awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ tẹ ọkunrin kan ti awọn ka aiyederu bebe Naira mewa aladipọ mọ lọwọ ni Ibadan ni ọwọn mu ọkunrin na, ti ọkunrin na si ṣe ileri pe ki nwọn ṣe oun jẹjẹ, oun yio mu wọn de ọdọ awọn ẹlẹgbẹ oun yoku ni ilu Aba.

Nitori eran yi ni Ọga Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ kan D. S. P. Z. Mẹ—mẹdu fi kọ awọn ọmọ iṣẹ rẹ lẹhin ti nwọn si tẹle ọkunrin na lọ si Aba.

Bayi ni ọkunrin na mu awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ yi de ilu Aba, ti o si tun mu wọn lọ si ọja kan ti nwọn npe ni Eke- oha nibiti o sọ pe awọn ẹlẹgbẹ oun bi amugbo, agunbẹ, roworowo, ọlọsa, igara ati da- ndakuda wa.

Irohin sọ pe, bi nwọn ti de apa ibikan bayi ni oja na, ni ọkunrin ti o mu awon Otelẹmuyẹ na wa lati Ibadan yeri mọ Olopaa kan ti o fẹ a lọwọ lowo. Nihin ni nkan ti sele

A gbo pe lesekese ni ọpọlọpọ giripa dide si awon Otelemuye na. Nwon na wọn bi i- kiku - bi i - yiya titi nwọn fi gba okunrin na silẹ lọwọ won.

Irohin sọ pe ọdidi wakati kan gbako ti ija na ti ṣẹlẹ ati pe ọwọ awọn Ọlọpa tẹ mẹta ninu awọn ẹala na, awọn si nwa awọn yoku kiri bayi.

Sugbọn titi di bi a ti akọ irohin yi, awọn ni Ọga awọn Ọtẹlẹmuyẹ na ngba iwosan ni ile iwosan ilu Aba.








## Aworan orisirisi

Aworan ti o wa loju iwe yi je orisirisi lati ile Geesi ati ile awon Jamani (Germany) Ninu aworan na, a ri awon eran osin (elede) ti awon bo diradara fun idije ohun esin ti nwon ti se koja nigbakan, bakanna ewe si ni aworan ti oke l'apa otun nṣe afihan opopo ọna Kan ni ilẹ awọn Jamani

# IROHIN NI ONILUJILU

## Ila-Ọrangun

ẸLẸMỌNA ti Ila—Orangun Oloye Adebayọ Atoyebi ni o ṣe aṣoju fun Orangun ti Ila Oba William Ayeni nibi ayeye ṣiṣi Mọṣalaṣi ti ile iwe giga Ila eyiti awọn Ẹgbẹ ẹlẹsin Musulumi kan fi ẹgbẹdọgbọnji Naira (N3,000) kọ laipẹ yi, o yin awọn Ẹgbẹ Musulumi na fun akitiyan ati iwa ifọwọsowọpọ wọn, o si fi Mọṣalaṣi na we ohun manigbagbe ni Ila-Ọrangun.

Ọkan ninu Oludasilẹ ẹgbẹ Musulumi na Alhaji O. A Ibiyẹmi tẹnumọ on pe o ṣe pataki ki awọn akẹkọ ni iwabi-Ọlọrun laarin wọn, o si rọ wọn lati maa pa ofin ati ilana ẹsin Islam mọ, ki a ma si ṣe ri iwa aigbọran ati jagidijagan laarin wọn.

Adele Baba Ẹgbẹ na Alhaji O. M. Adewoyin dupẹ lọwọ Ọrangun ti ila Ọba Ayẹni Ariwajoye, awon Oloye ati Ẹgbẹ Musulumi ilu na fun ifẹ ati inawonara wọn ti o mu ki eto na yọri si rere.

Bakanna, Alhaji Adewoyin sọ pe iru eto yi kanna ti nlọ lọwọ ni ile ẹkọ giga Ọyan ati Iragbiji lati ọwọ Ẹgbẹ Musulumi yi kanna, o si rọ awọn Ẹgbẹ Musulumi yoku ti Iwọ-Oorun lati maa ṣe bẹ gẹgẹ. Owo ti nwọn ri kojọ nibi ayẹyẹ ọjọ na to irinwo Naira (N400).

## Igbomina—Ekiti

A gbọ pe ija kan ti o ri wa laarin ilu Idofian ati Ọlọrunjare ni ihà ẹku Igbomina-Ekiti ni Ipinlẹ Kwara ti pari bayi, lẹhin ti awọn Ọtọkulu ilu mejeeji ti joko sọ ọ ni itunbi-inubi. Ọdun karun niyi ti a gbọ pe dukuu na ti wa laarin wọn

Awọn asiwaju ati ijoye ilu mejeeji ni nwọn panupọ pe, ki awọn fi pẹlẹkutu yanju ọrọ na laarin ara wọn ni yio ṣe ilu ikini-keji won loore ti nwon si gba bẹ.

Ninu ipade lati pari ija na, Oloye J G. Ẹkunrin soro pupo nipa irẹpo ati alaafia, ati anfani pupo ti totuntosi le ri gba ninu rẹ;

Lẹhin ti ija na ti pari, awon enia ilu wonyi gba lati maa san owo ori won papo sinu apo Ijoba Ibilẹ agbegbe wọn, ati pe awon yio maa ṣe ipade pẹlu ara won fun ilọsiwaju ati idagbasoke agbegbe wọn.

Alhaji Jimọ Akọlade dupẹ pupọ lọwọ Oloye Ẹkunrin fun wahala rẹ l'ori pipari ija na, o si fi i lọkan balẹ pe awọn yio ṣiṣẹ aṣekara fun ire agbegbe wọn na pẹlu ifẹ ati iṣọkan.

## Ikirun

Akirun ti Ikirun Ọba Lawani Adeyẹmi Oyejọla Keji ti kesi gbogbo awọn Ijọba Orilẹede yi lati wa nkan ṣe si awọn rukerudo ti o nṣẹlẹ ni aarin awọn ile ẹkọ giga Yunifasiti ti o wa kaakiri ilẹ Naijiria.

Ọba Oyejoja pe ipe na ni aafin rẹ ni opin ọsẹ ti o kọja nigbati o mba awọn ijoye re ati ara ilu rẹ ṣerọ l'ori gbigba iwe-ori Naira meji-meji fun ẹnikọkan ti o ba to iwe ori gba gẹgẹbi owo sisan fun omi ẹro.

Ọba na sọ pe ko dara bi iwa ẹhanna ṣe aṣẹlẹ laarin awọn ile ẹkọ giga gbogbo ki ilẹ Naijiria ma baa wa ninu ewu l'ọjọ iwaju, o si rọ awọn Alaṣẹ lati wa ọna bi opin yio ṣe de si iru iwa bẹẹ.

Ọba na fi kun un pe, iwa itiju ni eyi jẹ fun ilẹ wa, ko si yẹ ki iru rẹ waiye mọ.



Awọn Ṣoja Naijiria meji S. O. Ango (l'apa osi) ati S. L. Teldi ti nwọn kọṣẹ lati di Ọga Ologun ni ile ẹkọṣẹ ogun ni ilẹ Gẹẹsi. Nwọn ti pari ẹkọ ọlọdun meji na.




Ero afunninrichin ti awon Olepa fi maa mba mota won ti o ny'po lebora soro lati ile ise won jai ta wava ni Oga Ol-pa kan ndanwo yi ni oke - okun



Ọgbẹni ti ẹ awo yi Chay Blyth ni oun ni kan wa ọkọ oju omi yi aiye po lai duro. Ọọdunọjọ o din mẹjọ ni o fi rin irin ajo na, bi o si ti pari rẹ ni o ya aworan yi.



Ọkunrin na Chay Blth ti owa ọkọ oju mi yio po aiye ni ẹ awo yi bi iyawo rẹ Maureen ti aki i kuabọ.

# IDUPE



ỌBA ỌLADUNNI AJAGUNGBADE KẸTA
Ṣọhun ilu Ogbomọṣọ

# Alaiyeluwa Oba Oladunni Ajagungbade Keta, Sohun Ogbomoso

NDUPẸ o si nfi ẹmi imoore han si gbogbo enia; yala ti nwọn wa bi ẹnikọọkan tabi ẹlẹgbẹjẹgbẹ, tabi tẹ waya, pẹlu ẹbun lati fi ba Alaiyeluwa yọ ni akoko ayẹyẹ igbide ati iwuye rẹ ti o waiye laipẹ yi.

NI pataki, Alaiyeluwa Ṣọhun dupẹ lọwọ Ọlọla Gomina Ologun Ipinlẹ Iwẹ—Oorun Ọgagun Oluwọle Rotimi j c c; Ijọba Ipinlẹ Iwọ—Oorun, awọn Ọbalọba ni Iwọ—Ọorun, awọn Ọba ati Baalẹ igberiko gbogbo lati Oke-Ọya, awọn ile isowo nlanla ati awọn ile iṣẹ pataki—pataki kaakiri ilẹ Naijiria ati ẸGBẸ OGBOMỌṢỌ PARAPỌ nile, l'oko, ati ni idalẹ; gbogbo Ẹgbẹ Oninure ati Ẹgbẹ Olufẹ—ilu—ẹni, awọn ọrẹ, ojulumọ ati awọn afẹnifẹre gbogbo ti a ko lee ka tan.

## Ki ile Naijiria Maa roke ni akoko tiwa

**E. A. OKE**
(AKỌWE ṢỌHUN OGBOMỌṢỌ)

## Iyawo Soja

(Lati oju ewe kini) pe ninu ile rẹ ni o wa.

Siwaju si i, irohin sọ pe nigbati iyawo ṣoja na ri i pe awo ti ya, o gbe majele jẹ, o ṣubululẹ lẹsẹkẹsẹ, o si ku!

Irohin na sọ pe nihin ri ọkunrin na ti wọn aṣọ araa rẹ sọnu ti o si kan lu 'gbo pe "oju mi kil ribi."

Siwaju si i, irohin sọ pe lẹsẹkẹsẹ ni okiki iṣẹlẹ na kan kaakiri, ni awọn Ṣọja yoku ti o wa ni Bareke ba nle ọkunrin na kiri titi ọwọ won fi tẹ ẹ.

Orisun irohin kan ti o sunmọ iha ibi iṣẹlẹ na pẹkipẹki sọ pe, ọkan ninu Ṣọja ti o nṣọ ẹnu ọna Bareke ni alẹ ọjọ na ni okunrin na, ati pe, o nilati jẹ pe ero ajọṣọ laarin ọkunrin na ati obinrin tihin ni o mu ki eyi ọkunrin ni igboiya lati wọ iyara lọ iyawo oniyawo lọ; ati pe o nilati jẹ pe, itiju pa, nibo ni oun yio foju si ni o mu ki eyi obinrin gbe majele jẹ pẹlu.

Ṣugbọn bayi, a gbọ pe awọn Ọlọpa ti lọwọ si ọran na, a si gbọ pẹlu pe ọkunrin ṣọja tihin wa ni ikawọ wọn.

## Ademiluyi

(Lati oju ewe kini) enia mẹrin na ni: Lasunkanmi Akande, Layiwola Adigun, Kamoru Iṣọla ati Salami Ọmọtọṣọ; Adajọ na si paṣẹ pe ki nwọn lọ si ẹwọn ọdun mẹrinmẹrin fun jijẹbi ẹsun na:

Ọdaran karun Raufu Akanmu ni Adajọ ti kọ dasilẹ nigbati Agbẹjọro rẹ fi idi rẹ mulẹ pe ẹlẹjọ oun na kọ ni ẹjọ lati jẹ l'ori esun na.

Nigbana ni Adajọ sọ pe niti ọmọ Ọba Ademiluyi, ile ejọ ri i pe Agbọrandun ọro ile ti o ni iwe aṣẹ Ijọba lọwọ (licensed estate agent) ni o jẹ ni tire, enitI o ṣiṣe tire l'abẹ ofin lori ọrọ na, ko si si ohun ti o gbun un lọwọ tabi l'ese l'ori esun na. O ni pelu ododo ni ọmọ Ọba Ademiluyi fi ṣiṣe tire lori ọrọ gbigba owo na.


# Pools Pools

## Akilapa Naps

S2/147 ỌṢUNGBE—KUN RD ORANYAN IBADAN
17xxbk 12xx 22xx
PAIRS 28&29 1&32
Nje No 9 35 45 le ta omi

## Jovial Naps

NAP 22 24 36
Perm 1, 2, 10, 33, 3
M. O. Oketona,
15 Oke Ọla st
Apomu—Ikire
24xbk

**9**

**35**

**3 & 11** **45** **2o 21**


## ANFANI FUN O

Kinni iṣoro rẹ? Kinni ẹdun ọkan rẹ? Kinni o nru ọ loju? iwọ na nlalakala bi? Tabi ohunkohun nru ọ loju ninu Bibeli bi?

Ọfẹ ni a o fi gbogbo nkan wọnyi ṣe ẹ. Fi apo iwe ti o lẹ Stamp 5k mọ ara rẹ pẹlu addressi rẹ sinu iwe ti o ba kọ si mi:

Ero mi ni lati fi ẹbun ti a fun mi ran araiyẹ lọwọ.

Kọwe si-
Woli S. I. Owoṣẹyẹ
N6/763A Kabiawu Street
Mọkọla Ibadan.

ASỌTẸLẸ

"Ibi ni yio pa enia buburu ati awọn ti o korira olododo yio jẹbi" Ọrin Dafidi 34, 21

## Pipa Oruko da

BAYI ni lati sọ fun ara, ọrẹ Olubagbe, Ọga ati ojulumọ pe lati igbayi lọ, mo ti yi orukọ mi pada kuro ni Lateef Adeniyi Bamidele si Peter Adeniyi Bamidele.

—Peter A. Bamidele

PRINTED AND PUBLISHED BY THE PEOPLE'S NEWS YEMETU ILADOKUN P M B 5238 IBADAN OLOTU (EDITOR) LAWUYI OGUNNIRAN STAR PRESS